GO PLACES
IN A
HILLMAN
FROM
ARAB BROS
MOTORS LTD.

IROHIN IMOLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**Lakaye Orò**

Oninurere ti run kuro'li a i y e: ko sisi Olotito kan n i n u enia, gbogbo nwọn nba fun ẹjẹ ọmọnikeji rẹ. Olukuluku wọn nfi a w ọ n dẹ araku rin rẹ.
Ẹcìti o san julọ ninu wọi dabi ẹgun, iduro sisin julọ mu ju ẹgun ọgba lọ.

VOL. V No. 202 MONDAY JULY 3 — JULY 9 1961 KỌBỌ KAN (1d)

# Odaran kan sa Adajo ni ada o si bẹ lu'gbo, o di awati

OKIGWE:- IROHIN GBOJIKAN KAKIRI IPINLẸ ILA ORUN WIPE, ỌKUNRIN ỌDARAN, KAN, TI NWỌN NPE ORUKỌ RẸ NI GODWIN AGBU FI ADA ṢA ADAJỌ KỌTU IBILE NI ILU NA, HA! HA! HA! IRU RẸ ṢỌWỌN. BI A TI GBỌ ỌRỌ NA SI NIYI; ỌDARAN NA GODWIN AGBU TI ṢE SI OFIN IJOBA, ADAJỌ KỌTU IBILẸ NI ILU OKIGWE BA ṢA ỌDARAN NA SI KỌNKỌ ẸWỌN OṢU MEJI TABI KI O SAN PONUN MẸDOGUN.

Ssmọ-Samọ, Ada wa ni abẹ ọdaran na, lojiji ni Godwin ba tu gbiru kuro larin awọn Ọlọpa o si fa ada yọ, o kọlu Adajọ Ibilẹ Okigwe, o si ni Ada, piti piti nibiti A k ọ w e Adajọ gbo ntiraka lati salọ Godwin ni ki o duro gba tirẹ. Nigbati, ọdaran na ṣe aṣemaṣe yi tan, lojiji o ba kan lu igbo, awọn Ọlọpa lepare, nwọn si fi Ọkunrin na ṣe awati ninu igbo na, Agbọ wipe awọn ọdẹ ti kọ sinu igbo ti nwọn nwa Ọkunrin na kakiri inu igbo, nwọn koiti ri.

Orukọ Adajọ Ibilẹ na ni Ọgbẹni Igwe Okonkwo, orukọ Akọwe Adajọ ti o fi ara gbe ele ni Ọgbẹni Nwaṣuku.

Awọn Ọlọpa si nwa Ọdaran na lọwọ.



## Ile Eko University ti ile Ife

Aworan ti a nwo yi ni ipade kini ti awọn ajiroro lori ile ẹkọ giga Ile-Ifẹ (University of Ifẹ Provisional Council) ṣe ni ile Igbimọ tatijọ ni Ibadan

Ẹniti a si nwo ti o kọ ẹhin siwa ni Alaiyeluwa, Ọba Ọni Ile Ifẹ, on na ni nwọn npe ni Ọlọla Adesọji Aderẹmi on kanna ni Ọlọla Gomina fun agbegbe Ipinlẹ Iwọ Orun Ilẹ Naijiria.

Ile ẹkọ giga na jẹ ara abayọnri iwadi ti AṢHBY ṣe lori ẹkọ nigbati o sọ wipe o yẹ ki ani ileẹkọ giga pupọ si ni Naijiria.

## Oloye Awolowo soro inu re fun awon Oniwe Irohin Eko

Ni ọjọ kejidilogbọn oṣu kẹfa (28: 6: 1961) ni Oloye Awolọwọ fi iwe pe gbogbo awọn Oniwe Irohin ti o mbẹ ni gbogbo ilẹ Naijiria, Ghana ati awọn ti ilu Oyinbo jọ si, ile ẹgbẹ Action Group ti o mbẹ ni opopo Ita Martin, ẹsẹ gbogbo awọn Oniwe Irohin lo pejụ sibẹ, ati orisirisi awọn Oyinbo ajeji lati wa gbọ ohun ti Oloye Awolọwọ fẹ wi, nitoripe ti ẹnu Ẹga ni nwọn nfẹ gbọ.

Oloye Awolọwọ sọ w i p e. o yẹ ki a da ẹgbẹ kan silẹ, ti a o fun ni suna bayi pe, "All African People Congress" Isẹ ti ẹgbẹ na yio ma ṣe ni lati mojuto isẹ iselu, ẹnikẹni ti o ba si fẹ wọ ẹgbẹ yi ni lati wa bura wipe gbogbo ohun ti ẹgbẹ yi fẹ ni on yio ṣe.

Iwọnyi ni awọn ohun ti ẹgbẹ na yio ṣe:- (1) Lati gba Ominira ẹgba tan fun gbogbo awọn enia Dudu ti nwọn ti gba Ominira. (2) Lati fi asiko si ọjọ ti gbogbo ilẹ Africa yio bọ kuro ni oko ẹru, (3) Gbogbo ibudogun awọn ajeji ti o ba wa lori ilẹ Africa, ki a parẹ kuro (4) Ki a le awọn ajeji ti ko bikita fun ẹmi awọn enia Dudu. (5) Ki a le gbogbo awọn ti o nsọtẹ si iran enia kuro ki a si gba I j ọ b a kuro lọwọ wọn. (6) Ki a bu iyin, ọla, ati ọwọ fun awọn Ọba wa, Ijoye ati awọn Emir. (7) Ki a ṣe idasilẹ a j u m ọ s e larin awọn enia Dudu. (8) Ki a fi ọwọ ara wa ṣe ẹnu ala ilẹ olukuluku wa. (9) Ki a ṣe adehun owo ti a o ma na ni Afrika (10) Ki a si ri pe gbogbo ilẹ enia Dudu lo gba Ominira.

# Ajegboro dagba Nki Nyin O!

Mo ki gbogbo nyin, papa julọ ẹnyin Ọnkawe Irohin Imọlẹ, piri ni ologo ji a ki ba olokunrun ẹiyẹ lori ite. Emi Ọkunrin mẹta tun de, gẹgẹbi ẹ ti mọ mi pe bi emi ko ba ti ri ọrọ sọ nisẹ ni ara mi ki balẹ.

## Ẹ GBA NI? ẸNYIN ARA, AIYE DI RUDURUDU

Mo ki Ọgbẹni Fọlabi Ọlabimtan, o ṣe pupọ, mo ri ọrọ rẹ, mo si ka ni aka yeke, Ọpọlọ ti o fi kọ ọrọ na Ọlọrun ko ni jẹki o daru mọ ẹ ni agbari, Oluwa ko fi imọ kun imọ rẹ. Mo ro pe ti ọgbẹni Ọlabimtan ba wo ọrọ mi ti ọsẹ to kọja, Iwọ yio ri pe emi daruko rẹ sibẹ, ohun ti o mu mi ṣe bẹ ni pe, mo fẹ ka panupọ lati ba awọn enia Naijiria sọrọ papa julọ awọn Ọmọ Odua nipa iwa ainitẹlọrun, Imọtara ẹnikan tabi nipa ifẹ owo ati Ojukokoro ti o jẹ iwa ti o jọba lọkan wa lode oni.

Ṣugbọn inu mi dun pupọ nigbati mo ri ọrọ ẹ ninu oju ewe kẹrin ti iwe Irohin Imọlẹ t'ọsẹ to kọja yi, nitorina ni mo ba sare gbe Kalamu ati Tadawa mi pẹlu iwe mi lati le gbe ọ lẹsẹ, mo si nero pe ti mo ba ṣe bayi boya emi na yio ri enia gbe mi lẹsẹ lati le ba wọn sọrọ otitọ ti yio ṣe gbogbo ọmọ Naijiria lafani. Mo bẹ ọ Ọlabimtan maṣe jẹki ọrọ rẹ ma pẹ to bayi mọ nitori o to akoko lati le ba awọn enia Naijiria sọrọ papa awọn ọmọ Oduduwa.

Ọgbẹni Fọlabi Ọlabimtan, jọwọ mura lati jeki a ri pe awọn ema Naijiria fi iru iwa yi silẹ ki nwọn si pa ofin mọ, ati lati gbe ọmọ Oduduwa ga ki awọn Hausa ma si le pa iran Ọmọ Odud wa run.

HA! Ẹnyin ọnkawe Irohin Imọlẹ, ẹ ja ka panu pọ, ki a yan ẹni rere, ki a yọ ifẹ owo ni ọkan, ẹnyin ẹ wo awọn Hausa ẹnu wọn dọgba, Ibo ẹnu wọn dọgba, Kini ṣe? ti ẹnu awa ọmọ Odua ko fi dọgba? Ojukokoro ni ko jẹ. Mo bẹ gbogbo ọmọ Oduduwa eyiti o wa ni Ariwa ni tabi Iwọ orun lati jẹki a panu pọ ki a yan ẹni rere, ki ẹ jẹki a mọ inu ara wa, ẹ maṣe jẹki Hausa pa iran ọmọ Oduduwa run, ẹ jẹ ka fi mọ ṣe kan, ki a yan ẹni to ba wun wa ni aṣoju. Nitori ẹ jẹ ki a ranti awọn iran ti o yi nbọ, owe agba ni pe "Bi a ko ba to ri isu jẹ epo, a ma tori epo jẹ iṣu, ẹ ṣe iranti ti awa ba lọ tan ti awọn iran miran ba tun de nkọ? Ṣe ẹ fẹ ki wọn wa ni abẹ Hausa ni, nitorina mo bẹ nyin, ẹ jẹki a mu ifẹ owo kuro lọkan, owo fifun ni ko to enia, ki ẹ jẹ ka sowọ pọ ki a mu ẹni rere, ki a si dibo fun, kia mu ẹniti yio ṣe wa lafani ti yio si gbe awa ọmọ Oduduwa ga.

Mo bẹ gbogbo ẹnyin ọmọ Oduduwa ẹ ma ṣe jẹki ẹgbẹ Afẹniferere parun, ẹgbẹ ọmọ Oduduwa ni nṣe, ẹ jẹ ki a fi mọ ṣe ọkan ki a yan ẹniti o wu wa. Ẹnyin ẹ wo ariwa ẹgbẹ miran ki nwọle ju N. P. C. lọ, ẹ jẹ ka panupọ ki a yan ẹni rẹ. Nitori ohun ti a ba gbin ni a o ka, ohun ti a ba gbin silẹ loni ni awọn ọmọ wa yio ba nile.

Mo bẹ ẹnyin Oṣelu na, ẹ fi iwa imọtira ẹnikan silẹ, ẹ ṣe iranti pe ẹnyin kọ lẹ gbe ara yin de ibẹ, enia ni o gbe yin de ibẹ, nitorina ẹ ma ṣe rere fun awọn enia Ilu yin, igba ki lọ bi orere, aiye ki tọ bi ọpa ibọn, bi o pẹ titi ogun ọdun nbọ wa ku ọla, ẹ jọwọ ẹ ma ṣe dada si ilu, ki ẹ si ma fun awọn ti ko ti ri jẹ jẹ

Ẹnyin Ọmọ Oduduwa, ẹ fi Ojukokoro, Wọbiya, Ifẹowo silẹ, ki ẹ si mura silẹ lati sọ Naijiria di ilu rere ati ilu ti yio ni idagbasoke ninu ohun gbogbo ki o to di pe a o gba Ripọbiliki (Republic). E ma ṣe jẹki ilu wa di ilu ọlẹ, e ma jẹki ifẹ owo jọba lọkan nyin, ẹnyin Ọmọ iya mi ẹ ma jẹki o jẹ pe a gbe ẹwọn ti oyinbo silẹ ki a wa wọ oko eru ti enia dudu, ẹ jẹki a ni ifẹ ilu wa wa ju owo lọ. Enia rere ni a ko ba yan, ṣugbọn ẹnu wa ko dọgba, Wọbiya, Ainitẹlọrun ko jẹki a yan ẹni rere.

Ẹnyin Oṣelu Naijiria, ẹ ranti awa mẹkunu, ẹ ma ṣe jẹki a ma sun la bi, ẹ ranti pe Ibo tun mbọ.

Nitorina mo bẹ gbogbo enia Naijiria ki ẹ ṣe pẹlẹpẹlẹ, ki a rọra, ka panu pọ yan enia ataca, nitori aiye di rudurudu, ẹ maṣe jẹki wọn ma fi owo tan wa mọ ti Ibo ba nbọ, ki ẹ jẹki a fi ara balẹ yan eni rere ni Aṣoju wa.

Njẹ emi ọmọ Ọla nrele, emi ni asọrọ bi ẹni mọ tẹlẹ, Ọmọ Akin orele, Ọmọ Ajọba ma ba Ilu jẹ Oriburuku ki se temi Ọmọ Akitunde nrele Odigba.

For all your Printing Requirements

Invitations, Programmes, Hand Bills, Pamphlets, Advertising Material and all Commercial Jobbing

Send your Jobs to :-
MODUPE PRINTING PRESS,
16, Bamgbose Street, Lagos. Phone: 21985

Where Quality Print, costs less.




OTI TO DARA PUPO N!

Oja ko ta, ema Polowo oja yin sinu iwe Irohin Imole Ki e si ma ka ni Osese

IROHIN IMOLE DARABA

